LIBRARY

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No. 1,418 MONDAY AUGUST 2, 1965 (2D)

## ODARAN KAN JI EWURE GBE

IGBIRA:— Oju gba gbogbo enia ti fun Ọdaran kan, Seidu Audu, ẹni ọdun mẹrindinlogun ti awọn Ọlọpa mu wa si ile ẹjọ Ijọba Ibilẹ fun ẹsun ole jija ati ile fifọ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu keje ọdun yi.

Ọlọpa ti o ba Ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye wipe, ni ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu ti o kọja lọ yi ni ọdaran na lọ sinu ile Iyaafin Onowu, ti o si lọ ji ẹran ewurẹ iya na gbe ninu ile na nigbati o ṣe akiyesi wipe Obinrin na ti lọ si ọja lọ ta nkan

Ṣugbọn nigbati Obinrin na de lati ọja ti ko si ri ẹran ewurẹ rẹ, o bẹrẹsi kigbe kaakiri gbogbo adugbo wipe, ẹniti o ba gbe ẹran ewurẹ on, ki Oluwarẹ yara tete wa gbe ẹran na silẹ.

Ṣugbọn bi Obinrin na ti ṣe kigbe to ni ọjọ na ko si ẹniti o da Obinrin na lohun rara. Ṣugbọn awọn ara adugbo gbọ ti Ọdaran na npa ẹran ewurẹ kan ni ọjọ keji larin oru.

Nigbati awọn enia na ri ọrọ yi, ni nwọn ba lọ sọ fun Obinrin na wipe awọn gbọ igbe ẹran ewurẹ kan larin oru ti Ọdaran na npa.

Ko pẹ pupọ ni nwon ba lo ba Ọdaran na, ṣugbon ko gba awon enia na laye lati wo inu iyara rẹ lo woo bi awon puro moo ni tabi otito ni oro

WO OJU EWE KẸFA

ALHAJI ADEGBENRO SỌ PE:

# ẸGBẸ DẸMỌ TUN FẸ DA ROGBODIYAN SILẸ

ỌLỌRUNDA:- Gbogbo ilu lo gbojikan fun ariwo ayọ nla nigbati awọn enia gburo wipe, Alhaji Dauda Adegbenro, Adele olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati asiwaju ẹgbẹ Alatako ninu ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria de si inu ilu Ọlọrunda, ilu kan ni agbegbe Abẹokuta ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi.



ALHAJI D. S ADEGBENRO

Siwaju eyi ni gbogbo awọn enia na ti duro si oju ọna ti Alhaji Adegbenro yio gba wọ inu ilu na ni nkan bi ibusọ marun si ilu na, ti wọn si nreti rẹ pẹlu gbogbo awọn enia ti wọn jijọ lọ si irin ajo na.

Awọn ọdẹ ilu na gbogbo ni nwọn gbe ibọn wọn lọwọ lọ pade Alhaji Adegbenro ni oju ọna pẹlu gbogbo awọn obinrin ọlọja ti nwọn wa ninu ilu.

Awọn enia na ni inu awọn dun nigbati wọn gburo pe Alhaji Adegbenro nbọ wa bẹ awọn wo ninu ilu na, gbogbo awọn si ti ṣe ipinnu pe, enikankan ki yio lọ sibikan ni ọjọ ti Alhaji na ba nbọ.

Pẹlu ilu, aro, ṣẹkẹrẹ ati orin didun ni awọn obinrin nkọ bi nwọn ti ṣe nlọ ni oju ọna na titi nwọn fi jo wọ inu ilu na.

Gbogbo awọn ti nwọn wa ninu ilu na ni nwọn ko lọ si oko wọn ni ọjọ na ti nwọn si nreti Alhaji Adegbenro pẹlu awọn enia rẹ, Nigbati mọto awọn enia na to lati ibiti nwọn i wa pade Adegbenro, awọ kan ti to wọn a in ilu nigbati awọn kan si wa ni biibusọ marun sinu ilu na ti nwọn nkọrin.

Pẹlu ilu, orin ati ijo ni awọn enia na jo lati ibiti awọn i wa pade rẹ titi ti nwọn si fi wọ inu ilu.

Kẹkẹ pa ohun mọ awoko lẹnu nigbati Alhaji Adegbenro bẹrẹsi ba awọn enia na sọrọ lori ibo ti mbọ yi ni ipinlẹ na.

Alhaji Adegbenro ni on ti ngbọ hunnuhunnu labẹlẹ wipe ẹgibẹ Dẹmọ npete lat da rogbodiyan ati rudurudu silẹ ninu ile Igbimọ nigbati nwọn ba nṣe Ipade lowọ, eyiti awọn yio ṣe lai pẹ yi, nipa ṣiṣe bayi, Apapọ Ijọba Naijiria yio fi tun paṣẹ wipe ki ẹgbẹ Dẹmọ tun ma ṣe akoso Ijọba na lọ fun bi oṣu mẹfa si,

Alhaji Adegbenro tun sọ ninu ọrọ rẹ pe lati igbati on ti gbọ ọrọ na ni awọn ti lọ fi ọrọ na han awon Ọlopa ki nwon le ba mo ohun ti ẹgbẹ Dẹmo fẹ ṣe nişişiyi silẹ ki oro na ma ta ṣe kan wọn ni ojiji

"PAJAWIRI"

Gbogbo awọn enia na ni wọn ya ẹnu silẹ ti wọn fẹ le ma pade mọ nigbati Alhaji Adegbenro nsọ pe awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ fẹ da rudurudu na silẹ ninu ipade ti awọn ọmọ ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ na yio ṣe laipẹ yi ki apapọ Ijọba le tun ofin Pajawiri, iru eyiti Ijọba na ṣe ninu odun 19-62, eyiti o ba ofin na jẹ di oni yi

Ṣugbọn inu gbogbo awọn enia na lo dun ti wọn si tun palẹwọ nigbati Alhaji Adegbenro sọ pe, ọrọ na ti wa ni ọdọ awọn Ọlọpa nisisiyi wọn y o si da seria fun ẹgbẹ oṣelu yio wu ti o ba da rudurudu silẹ ninu ibo ti nbọ yi ẹni yowu ti o le jẹ

O tun so pẹlu wipe ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakuko ko ni ohun kan lati bẹru rẹ rara ninu ibo yi

Alhaji Adegbenro

WO OJU EWE KẸFA

## Atilade, Ero Ilu Oyinbo, Ẹ ka'Bọ O

EKO:— Irohin ko to afojuba ni are aladun ati orin ayọ ti awọn ọmọ Ijọ Onitẹbọmi "Gospel" Baptist Church" ṣe ninu ile Ijọsin wọn ni Nọmba 70, Apọngbọn Street, Eko ni deede agogo marun irọlẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu ti o kọja lọ yi

Onirohin wa Ejon gboro fi ye wa wipe, ni ọjọ ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu yi ni Ẹniọwọ Oniwasu E. A Atilade, ẹniti iṣe Oniwasu Ijọ na ni Eko, Ebute - Mẹtta ati gbogbo agbegbe Eko de lati ilu Ọba Oyinbo nibi ti o gbe lọ tun kọ iwe sii nipa bi atiṣe kọ



Ẹniọwọ E A Atilade

awọn iwe ti nwọn nlo ni gbogbo awon ile iwe yika gbogbo aiye

Gbogbo awọn ẹbi, ọrẹ, ati gbogbo awọn ọmọ Ijọ Onitẹbọmi ni nwọn lọ pade Oniwasu Atilade ni ibudo ọkọ oju omi nigbati o de lati ilu Oyinbo ni ọjọ na.

Nigbati o ti ku nkan bi ọjọ mẹta ti Atilade yio de si ilu Eko ni awọn enia ti bẹrẹsi de lati Awẹ Ọyọ, Ibadan, Abẹokuta, Ilọra, Akinmọrin, ati bẹẹbẹ lọ ti ile ati ode ko si gba ero mọ ki ọjọ ti Oniwasu Atilade yio de to pe !

Nigbati o di deede agogo mejila ọsan ni ọkọ oju omi na gunlẹ si ibudo ọkọ ojuomi.

Ariwo ayọ nla ta gee gbogbo awọn enia si sare lọ pade Oniwasu Atilade ni oju ọna bi nwọn ti ri i ti o njade bọ lati inu ọkọ oju omi On na si fi t'ẹrin tayọ pade awọn enia loju ọna.

Lẹhinna ni gbogbo awọ enia na wa wọ mọto Ayọkẹlẹ wọn ti nwọn si lọ si Ṣọọsi lati lọ gbadura si Ọlọrun fun riri ti awọn tun ri ara awon ni alafia.

Lẹhin eyi ni Oniwasu na wa lọ si ile rẹ

W o oju Ewe Kẹfa

# Mo Ba Irohin Imolẹ Yọ

Lati Ọwọ J. O SHOYINKA Mushin

Loni, Iwe Irohin Imolẹ nṣe ọjọ ibi kejọ ti a da silẹ lati ọwọ Ọgbeni Adeniji ti iṣe Oladari ile iṣẹ na titi di oni, Oluwa Alanu yio ma ṣe ọwọ yin ni eso, iwaju ni ẹ o ma lọ, ẹ ko ni rẹhin lailai.

Nitootọ gbogbo ọrọ mi ni o ma ndabi itan, bi awọn onkawe yio ba wi, nwọn a ni Shoyinka gbe itan de, nki ṣadede pitan bikoṣepe ọrọ itan ba ṣẹlẹ. Ni ọdun kejọ sẹhin, Ọgbẹni Adeniji ti iṣe oludari ile iṣẹ na ni o wa gbogbo iṣẹ na mọ aiya, nitoripe on nikanṣoṣo ni nṣe iṣẹ oludari dapọmọ iṣẹ Olotu ṣugbọn nipa aranṣe Oluwa iṣẹ na nlọ deede.

Nigbati ọjọ ngori ọjọ, ti oṣu ngori oṣu, ti ọdun si ngori ọdun igbega ati ẹdọ Ọlọrun wa de ba iṣẹ na. Igbega na si bẹrẹ lori Olotu awa isisiyi Ọgbẹni Tunji Adeṣun, onigegewura nitoripe asiko ti o gori aga Olotu ni Iwe Irohin bẹrẹsi jade lojojumọ IWE IROHIN YORUBA KINI TI O NJADE LOJOJUMỌ

Nigbati mo kọkọ gbọ pe, iwe irohin Imọlẹ yio ma jade lojojumọ, mo mi kanlẹ hẹẹn, mo si sọ li ọkan ara mi pe, njẹ ala ti oludasilẹ ati Olotu iwe na



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

ha le ṣẹ bayi ? Ki i ṣe pe nko wa ilọsiwaju iwe irohin na ṣugbọn iriri mi gẹgẹbi Olotu Iwe Irohin Yoruba nigbana, ti mo se ro bẹ, toripe ohun ti oju emi ati awọn alabaṣiṣẹpọ mi nri ki a to le ma gbe Irohin Yoruba jade lọsọsẹ ko ṣe fẹnu sọ, anbọsibọsi ẹniti o sọ pe, on yio ma a gbe ti on jade lojojumọ Oluwa ṣe Amin si i. ala awọn mejeji si ṣẹ. Kii ṣe ti asọdun. Iwe Irohin Imolẹ ni iwe Irohin l'ede Yoruba kini ti o njade lojojumọ ni Naijiria.

AWỌN AKỌWE IWE IROHIN NA GBADUN

Kọnkọ ole ti o ba akere fo yio ṣẹ ni apa, ni ti ọrọ iwe Irohin Imọlẹ, nitoripe ijinlẹ yoruba ni olotu iwe na nṣe sinu rẹ, gbogbo awọn agbeka ọrọ ti o nsọ, ko si ni afiye rara.

Ẹnyin olukawe Irohin Imọlẹ papa yio jẹri si ọrọ mi pe, ko si meji Irohin Imọlẹ ni Naijiria.

Awure ni Irohin Imọlẹ je fun awọn ọtaja ati oraja. Ẹ dakun ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ, ẹ maṣe ṣi ọrọ mi gbọ toripe ọrọ ỌJỌ IBI IROHIN IMỌLẸ ni a nsọ, ṣugbọn odabi ẹnipe mo npọn iwe yi pupọ, ẹnikẹni ni o mọ ninu yin pe, ti enia ba nṣe ọjọ ibi rẹ, ohun rere ti wọn ba mọ nipa rẹ, ni wọn yio ma fi yoruba rẹ

Bi mo ti ṣe mọ riri iṣe iwe Irohin Imọlẹ to, ni yio ṣe tun mẹnuba ipolowo ọja fun otaja ati oraja.

Ẹnikẹni ti o ba npolowo ọja rẹ sinu Iwe Irohin Imọlẹ, ko ni mọ aitaja ọja agbana ko si ni wọ inu igba rẹ lailai, nitoripe gbogbo agbaiye ni nwọn yio ti ma a ranṣẹ, ọja lọdọ rẹ, ẹsẹ awọn onibara, ti nwọn wa larin ilu ko ni wọn lọdọ rẹ. Iwe Irohin Imọlẹ yio ṣe eyi fun nyin ti ẹ ba polowo ọja yin sinu rẹ,

Bi Ifa ba da Babalawo lọla a dupẹ lọwọ Ifa, Alfa a si maa dupẹ lọwọ Anabi bi Ọlọrun ba ṣore fun, bakanna si ni Onigbagbọ a maa dupẹ lọwọ Olugbala ti o ba siju Anu rẹ wo o. Nje ẹnyin Olukawe Irohin Imọlẹ ẹ ta mi kọ orin yi lati fi yin Oluwa l'ogo pe Iwe Irohin Imọlẹ goke agba.

Orin na lo bayi

A f'ọpẹ f'ọlọrun
L'ọkan ati l'ohun wa
Eni ṣ'ohun 'yanu
N'nu enitaraiye nyọ
Gba ta wa lọmọ ọwọ
On na lo ntọju wa
O si f'ẹbun ifẹ
ṣe itoju wa sibẹ
Ọba Onib'ọrẹ

Wo Oju Ewe Karun

# ORO SOKI

Lati Ọwọ EBENEZER ADENIJI
Oludasilẹ Iwe Irohin Imolẹ

Mo ki nyin ẹnyin Oba ati Ijoye nilẹ Naijiria, mo si ki gbogbo ẹnyin Iya ati Paba mi, papa Iya mi Oduọla ati arẹwa Baba ti o bi mi l'ọmọ ti o ti fi ilẹ bora bi aṣọ, ọrun rere Baba ti ta ki Oluwa mu erupẹ tuburu kuro loju rẹ.



Ọgbẹni EBENEZER ADENIJI

Ko ni dun to, bẹ si ni ko ni kun to ti nko ba sọrọ diẹ lori iṣẹ nla ti Ọlọrun Ọga Ogo gbe kalẹ lorilẹ ede (Yoruba) lati ọwọ emi Ebenezer Adeniji, oludasilẹ Irohin Imọlẹ.

Mo dupẹ pupọ lọwọ gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ ti ẹ nṣe inawo lojojumọ Oluwa ko ni jẹki apo owo nyin gbẹ.

ẸBẸ FUN IRANLOWỌ

Dajudaju l'agbara Ọlọrun Iwe Irohin Imọlẹ ti fi idi mulẹ na, ṣugbọn Iranlọwọ ati ifi Ọwọsowọpọ ẹnyin ọmọ Yoruba ni mo wa nbẹbẹ fun pe ki iwe Irohin Imọlẹ l'ede wa yi maṣe parun nitori anfani awọn ti ko gbọ Oyinbo.

Ore ti a ṣe fun adiẹ ko ...be bi opẹ titi omitoro adiẹ yio kanni lẹnu. Mo nilati dupẹ pupọ lọwọ awọn Oluranlọwọ gbogbo paapa lọwọ Ọgbẹni Alhaji Babatunde Jọsẹ Oludari Iwe Irohin Daily Times Ọgbẹni Adebayọ Olotu Daily Express, Pilot, ati Morninig Post.

Kiani nbajẹ ki ngbagbe awọn ogẹgẹ wura awọn enia bi Ọgbẹni Ọlabintan Ọgbẹni J. O Shoyinka, Alhaji Y Disu, Oloye Erukobodo Ọgbẹni Jaiye S O Ọgbẹni Olurebi Williams Ọladipo Yẹmitan. awọn wonyi ni igi lẹhin ọgba fun, Irohin Imọlẹ.

adura mi fun wọn ni pe ki Ọlọrun ki o ran awọn papa lọwọ ninu igbokegbodo awọn ọna ti nwọn ngba fi ran iwe yi lọwọ Oluwa ko ni fọ wọn loju inu ati tode ao ba ara wa ṣe e pẹ.

Ori kọ ni ọjọ ọrọ mi ni tori ayọ kun ọkan mi, ẹmi ni yio si ma sure fun gbogbo ẹnyin ti ẹ nlepa itẹsiwaju Irohin Imọlẹ ni gbogbo ọjọ aiye nyin,

Inu mi yio dun lọpọlọpọ ti ẹ ba le ba mi gbe orin mi yi:

IWE ORIN C. M. S.
556 ẹsẹ 1—4

1. Fun anu ti pọ b'iyarin,
Ti mo ngba l'ojuumọ
Lati ọdọ Jesu Oluwa,
Ki l'emi o fi fun ?
2. Kini ngo fi fun Oluwa,
Lati inu ọkan mi?
... ṣẹ ti ba gbogbo rẹ jẹ,
Ko tile jọmọ nkan
3 Eyi l'ohun t'emi o ṣe,
F' ohun t' o ṣe fun mi;
Em' o mu ago igbala,
Ngo kẹ pe Ọlọrun
4 Eyi l'ọpẹ ti mo le da,
Emi oṣi, are,
Emi o ... a sọrọ ohun Rẹ,
Ngo si ma bere si.

## Iwe si Olotu Irohin Imole

# EMI AṢE ỌPO ỌDUN O!

Mo ki gbogbo enyin onkawe Irohin Imọlẹ l'mọde ẹlẹgbe mi ati lagbalagba, ẹ ku iṣẹ o.

Ojẹ idunun ati ayọ nlanla fun mi lọjọ oni fun anfani ti mo ni lati ki enyin onkawe Irohin Imọlẹ ku oriro ati lati ba Iwe Irohin Imọlẹ yọ ti ajọdun ọdun kẹjọ ti Iwe Irohin na daiye.

Ni ọdun 1956 ti baba mi Da iwe Irohin-Imọlẹ na sile ni mo di ọmọ ọdun mẹrin, ṣugbọn loni, mo ni ayọ pupọ pe loni kunrin, ti baba mi nṣe fajọyọ ajọdun ọdun kẹsan ti o da Iwe Irohin Imọlẹ sile ni mo di ọmọ ọdun mejila ati oṣu mẹta.

Nitorina mo fi epi kẹ ọ pẹlu ayọ ati inu didun lati dupẹ pupo lọwo enyin onkawe Irohin – Imọlẹ ẹ ko inawo ojojumọ ibiti ẹ ti nmu owo na ko ni tan nibẹ o, Oluwa ko ni so Imọlẹ nyin di okunkun lailai, ẹ ko ni ṣe ti o.

Emi ni,
Adekunle Adewale Adeniji
EKO

gba mi ni aye die ninu iwe nyi to un fun ogbon ati oye lati kesi Ijọba apapọ Ile Naijiria lati fi kun awọn Tesan awọn ọlọpa ti Ijoba Apapọ.

Mo rope eleyi jẹ ohunti o ṣe pataki pupo ju fun awa enia to gbe ni ilu Eko ati pe opolopo awọn odaran lo jẹ wipe awon olopa yio mu to jẹ pe Centre Police Staton ni nwon yio mu lo nigbati kosi Ọgba awọn olopa ni tosi.

Ọpọlopo awọn nkan miran lo jẹ wipe a nṣelẹ ṣugbọn ki awọn ọlọpa tabi ki nwon to ranṣẹ si awọn Ọlọpa pe iru nkan bayi ṣele, ki awọn olopa ti de bẹ yio ti salo, Inu awa Olugbe ilu Eko yio dun bi apapo Ijoba ba le tete ṣe eleyi fun wa ni kiakia. Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
Kazeem Surajudeen
IJẸBU-ODE.

## Idahun Si Ibere Moses Alawẹ

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi ni aye lati dahun si ibere Ọgbẹni Moses Alawẹ ti ilu Esie eyiti O sọ pe awọn Wundia ilu na ma nloyun pupọ bayi.

Inu mi yio dun bi Ọgbẹni Moses ba le lọ ronu rẹ jinlẹ lati lọ mọ daju pe ko si ninu awọn ilumiran ti iru nkan ko ti nṣẹlẹ, ṣugbọn mo fẹ ki Ọgbẹni Alawẹ lọ mọ daju pe iru ọrọ ti o nsọ ti jade yi jẹ ohunti ta abuku si ilu na,

Gẹgẹbi ọrọ awọn alagba ti o lọ bayi pe "Egbe ni fun Ọmo na ti o fi owo osi juwe ile baba rẹ. Mo fẹ ki Ọgbẹni yi lọ mọ daju pe ọrọ Omugọ ni o gbe jade ninu iwe Irohin Imọlẹ eyiti o jẹ wipe itiju lo tun le fun on kanna.

Mo tun kesi Afọlabi Onijala lati lo mọ pe enia kanna ni on pelu Moses lori ọrọ ti nwọn sọ nipa awọn Wundia ilu Eṣie Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
G. S Ọmọ Esie
ESIE.

## Aṣiri ẹgbẹ Dẹmọ tu

Inu mi yio dun bi olotu ba le gba mi laye die ninu iwe Irohin Imọlẹ lati fi ye awọn ẹgbẹ Dẹmọ pe aṣiri wọn ti atu nigbati eto owo koko eyiti Dokita Okpara tu aṣiri wọn nigbati o de Eko, Oloye Awoṣika lo ba wọn gbẹjọ wọn ro ti Oloye Adebọ si gba oku wọn sin

Gbogbo ibiti ẹgbẹ na de ni wọn ti ntẹ bẹ na ni wọn tẹ ni Ile-Ifẹ ti awọn ẹgbẹ ipinlẹ Iwọ Orun kọ ẹhin si wọn, eleyi to ohunti o yẹ ki o ti ẹgbẹ Dẹmọ loju.

Ṣugbọn ohunti awa enia ipinlẹ Iwọ Orun nreti bayi ni eto idibo to mbọ eyiti a lero pe lagbara Oluwa pe ẹgbẹ UPGA ni yio bori rẹ ti gbogbo enia yio ni itẹlọrun yio wa fun gbogbo wa.

Gbogbo ọna ibiti awọn ẹgbẹ Dẹmọ ngba ni yio jakulẹ, ati pe a si mọ pe ti wọn ba le gbe omi ti wọn fi ibọn fọ ati aiyelala fun gbogbo awọn oṣiṣẹ Ijọba nou tan awa si mọ pe ẹgbẹ Dẹmọ yio kuna ninu ibo na labẹ ara Oluwa.

Mo tun fẹ ki Alhaji Ahmadu Bello lo mọ pe ko le si irẹpọ laida awọn olori oṣelu to nṣe ẹwọn sile ati pe ki a yara jawọ kuro ninu ofin oni kumọ ti a npa ni ipinlẹ Ariwa, olotu mo dupẹ fun ayẹ ti ẹ gba mi

Emi ni
Alhaji L Ade Otubu
Ijẹbu Ode

## Tesan Awọn Ọlọpa Ko To

Ine mi yio dun bi Olotu ba le

# E Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumo

# EGBOGI JEDIJEDI



CYCLOVEN

Aworan egbẹ yi fi han gba ngba ibiti jẹdijẹdi to wa lara rẹ ti nyọ ọlẹnu ni gbagbogbo Ibẹ ni a npe ni omusu tabi iho idi enia ibiti nma ngba iṣe igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ikan ninu amodi ti o buru, ni pataki fun okunrin ti o si ṣoro pupo lati ṣe iwosan rẹ tan patapata.

Ọpolopo egbogi li o wa t'a nta kakiri ode isisiyi ti nwọn ma npolowo nwọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya ni a le ri mẹwa ninu awọn ogun to le ṣe iwosan arun daradara.

Awọn elomiran lero wipe boya bi wọn gbe lo si ile iwosan lati lo ge eyiti o ba nyo jade ni omusu on nipa bẹ awọn bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa koro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyoku rẹ yio si tun bẹrẹ bakanna Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ aiko maṣe li bọnsẹ deede tabi lojojumọ, gigun kẹkẹ ologere Basikulu pupọ ẹlomiran ẹwu ẹran Suga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba jẹdijẹdi orisirisi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o nyo sode ninu omusu tabi ti o ma nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnṣe tabi ti nrin o ninu omusu rẹ ti o ba jẹ bẹ bere egbogi CYCOVEN ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣe wa idi rẹ ki o si dan wo o ri daju wipe Iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata ti a ta nigboro Naijiria bere ni:-

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Lagos
Phone; 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji

ADEDUN CHEMIST
14,. Wakeman Street, Yaba

Ipolowo Oja Rẹ ko Ti Yege
*Nitoripe*

O KO TI POLOWO ỌJA RẸ

SINU IWE IROHIN IMOLE
T'ODUNKA FUN GBOGBO ENIA

KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI

ADVERTISEMENT MANAGER
IROHIN IMỌLẸ
16 Bamgboṣe Street, Phone 21985 Lagos

Iwo Ha Nfẹ Ile L'Eko Bi

| | |
|---|---|
| Room | £5 |
| Room and Parlour | £6 |
| Room and Shop | £15 |
| Room and Parlour | £12 |
| Shop at Idumagbo | £5 |
| Room | £4 10 |
| Room | £4 |
| Room | £5 |
| Room/ Parlour | £11 |
| Flat | £18 |
| Flat | £20 |
| Shop | £3 |

Ti o ba nfẹ okan ninu awọn ile wonyi yara tete lọ ri Ọgbẹni ODUS:— 187, Bamgboṣe Street Lagos.
Ni deede agogo merin irọlẹ si agogo mẹfa Irole. Ijafara lewu anfani nla kanni eyi jẹ fun o pe, o ri ile l'Eko

# Ẹgbẹ UPGA Ti Mura Ibo Silẹ

EKO:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa ni ọjọ ọjọ' ru ti ẹṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu yi ni a ti gbọ wipe ẹgbẹ itẹsiwaju (UPCA) ti ṣe eto lori eto idibo si ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko eyiti uwọn yio ṣe idibo rẹ ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu kẹwa ọdun yi.

Ninu eto ti awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA ṣe na ni nwọn fi ọwọ si i pe ibiti ẹgbẹ Afẹnifẹre ba ti mu enia silẹ pe ẹgbẹ Alakukọ ko ni mu enia silẹ ati wipe gẹgẹbi awọn omọ ẹgbẹ mejeji na tiṣe wọle ninu idibo ti nwọn ṣe ninu ọdun 1962 ni nwọn yio tẹle- ibiti awọn ọmọ ẹgbẹ kọọkan ba ti wọle lasiko na ni nwọn yio mu enia silẹ lati di ibo fun un.

Ninu irohin to jade lati ọwọ Akọwe eto ipolowo ẹgbẹ Oloye F U Anyiam ti ṣe alaye pe lori eto ẹgbẹ UPGA ti ṣe silẹ ni nwọn ni lati tẹle lori eto idibo si ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko to mbọ yi.

Ni ipari ọrọ rẹ, F U Anyiam tun ṣe alaye pe ẹgbẹ mejeji na ti papọ lati ṣe eto lori isowọpọ ti nwon gbọdọ ni lati gbogun ti awọn ẹgbẹ oṣelu ti nwọn jẹ ọta si ẹgbẹ itẹsiwaju UPGA ati wipe ki nwọn si mura lati pa ẹgbẹ to ba ti jẹ ọta wọn run patapata ninu idibo to mbọ yi.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Iwọ yio ri irohin ka gbọ ni owurọ yi, irohin na nigbati o ba gbọ, yio jẹki ọkan rẹ fuyẹ

PISCES (Feb 21 – Mar 20) Awọn irawọ ọrun yi ṣe iralọwọ fun ọ bi iwọ ba le ni ajumọṣe pẹlu awọn ẹlomiran ti o nifẹ si ọ ti o si fẹ ọ delẹ.

ARIES Mar 21 April 20) Ire nla kan ti o jọ enia loju yio kan o lara loni bi ọwọ ba tẹ ire na o yẹ ki o rọnu wo daradara ki o to da ṣe ri ya fun nu.

TAURUS (April 21 May. 20) Bi o ba ngbero lati ṣe ohun kan nṣe ni ki o gbe wo ki owo iwaju ati bi igbẹhin rẹ yio ti ri.

GEMINI (May 21 June 21) Iwọ yio gbọ irohin ala dun kan gbọ nitorina ki o maja ki inu rẹ si ma dun si gbogbo ẹniti o ba bapade loni ki o si fi ara balẹ.

CANCER (June 22 July 22) Nipa ọgbọn ti Ọlọrun fun ọ ni iwọ yio fi tu imọ gbogbo awọn to ngbero lati ba tirẹ jẹ Iwọ ko le ṣe alairi ohun ibinu nṣe ni ko fi ọwọ wọ nu.

LEO (Aug 23 Sept 22) Ọkan rẹ yio balẹ inu rẹ yio si dun loni ṣugbọn ohun kan ti iwọ ko ro tẹlẹ le mu lati fẹ yio mu on tio gbero pada maṣe iwọ ko ni ri ibanuijẹ ni bẹ ṣugbọn maṣe dajọ idakuda

VIRGO Agu 23 Sept 23 Bi o ba ti fi ọrọ si ibẹ ni ki a ba ọ nipa bẹ, igbẹhin rẹ yio dun bi oyin, maṣe fi ọkan si wipe tinu mi ni ma ṣe.

LIBRA Sept 24 Oct 23 Gbogbo awọn irawọ ọrun lo ti mura lati ṣe rere fun Ṣugbọn ki o maṣe fi eti si ọrọ kọrọ ti wọn nse kakiri.

SCORPIO Oct 24 Nov 22 Ohun gbogbo ti o ba ṣe lori, adun ni igbẹhin rẹ yio jẹ, ṣura lọdọ awọn alay nu sọ, sa lo ọgbọn tirẹ diẹ ẹnu yio ya ọ lati ri adun ti yio ti sẹ yọ jade.

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Irohin kan ti iwọ yio gbọ yio jẹ i o ṣe pin u rere ka opolọpọ nbẹ fun ọ

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21 Iṣẹ rẹ yio pọ iojọ loni ṣugbọn bi ọrun ba ti nkun ọ yara ki o lọ fi ara lelẹ.


## Kini E Nduro Fun

Bi o ba ni Aṣọ fun fifọ Ati lilọ bi wolen aṣọ oke, Tafẹta Sapẹti ati orişirişi aṣọ ti oba ni fun fifọ ati lilọ ni iṣeju kan.

TETE GBE WA SI ỌDỌ

### JOYCE LUNDRY DYNG & DRY CLEANING SERVICE

9, Fatiregun St, Brickfield
Apapa Road Ebute Mẹtta

Kia ni ao si fọ ti o ri gba ni ẹsẹ kanna A lo wa gba ni ile rẹ, ki a ko pada fun ọ bia fọ tan kọ nọmba ile rẹ ranṣẹ si wa dan wa wo lẹkansoso ki si ri bi iṣẹ wa ti ri

Owo poku ni a si ngba.



EGBOGI AWỌN ILU FARANSE

## TESSYDRE

Fun Ọmọ—Ọwọ ati Ọmọde gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi hauuhaun ti meji iru fẹ bẹ kosi kakiri igboro ilu Naijiria fun itọju ọmọ ọwọ ati ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu ẸHIN ẹnu wọn pẹlu rọrun laisi wahala rara tabi aiko le sun yala losan fun awọn iya wọn gbogbo Ọgọrun orisirisi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ ṣugbọn ko si eyi ta le fi we egbogi Tessydre rara o, Ọlọgbọn di ori ẹja ma pupọ ninu awon ara ilu Saro ati awọn Agọnyin (GHANA) mọ egbogi yi dajudaju on ni nwọn si nlo fun awọn ọmọ ti wọn ba ṣẹṣẹ bi titi fi di nkan bi ẹmọ ọdun mẹwa gbako . Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọka ori aiperi ori inu iwọ osi fẹkun fẹkun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ şişan gburu tabi aikolokun ninu ara, sisu inu kun kun aiorun ati orisirisi awon amodi tabi aisan ti o mo nyọ awon ọmọ ọwọ lẹnu nigba Ehin HIHU gbogbo Tessydre a ma mu kichin ẹnu ọmọ rẹ legbara gidigidi ati san pẹlu.

Awọn ọmo ti o n l o egbogi yi ki saba ma sarẹ rara niwọn igbati nwon ba ti nlo deede, ti otutu ki si le ri ayo ati duro ni igbaiya wọn ti wọn njẹundaradara nwon sun gbadun pẹlu yio si jẹ ki erigi san pẹlu.

NIGERIAN MEDICINE STORE
4 Tinubu Square Lagos
WATERLOO MEDICINE STORE
8, Pamchurch Street Lagos
Phone 22872 Nigeria (Ọja Ita Faji)

# Irinajo Lati Eko Lọ Si PortHarcourt

LATI ỌWỌ ẸṢỌ

Mo ri pe bi mo ba ṣe irohin ohun ti mo fi oju mi ri lori irin ajo mi ti o gba mi ni ọjọ mẹrin gbako tọsan toru, ọpọ enia yio nifẹ lati ṣe bẹ pẹlu Mo bẹrẹ irin ajo mi lati Teṣan Iddo, ṣiṣi ti ọkọ wa ṣi ko duro ni ibikan titi o fi de Teṣan Agege lati Eko si Agege, ọna kan gbọrọngọndọn ni, nko si ri iru opopo bẹ pe o pe meji titi mo fi de Pọrta, Nigbati ọkọ gunlẹ si Agege, mo ra akara gbẹntu jẹ Lati Eko si Agege jẹ papa.

Ọkọ wa ṣi kuro ni Agege, ko si duro titi o fi de Itori lati mu omi lati Agege si Itori jẹ igbo ẹgan ko si si ohun kan ti o ṣe paa taki ti enia le mu ẹnu ba Mo ra iṣu sise jẹ ni Itori Ọkọ wa wa tun ṣi, o kọri si Aro ni Abẹokuta Ni Teṣan Aro, nwọn ko nta oriṣi nkan meji ti o tayọ ọsan or mbo mimu, bi enia ba si naga, yio ma wo Odo Ogun li okere, la ti Itori si aro jẹ papa Ọkọ wa tun gbera, o di Olokemeji Ki a to de ibẹ enia yio ma ri odo Ogun bi o ti nṣan lọ iwọ yio si ri awọn oke meji na, ọkan ni apa ọtun ati ekeji ni apaosi, bi o ba fẹ ri ṣonṣo awọn oke na bi iwọ ko ba fi ọwọ mu fila rẹ dani yio ṣi bọ silẹ nitoripe larin awọn oke meji nwọnyi ni ọkọ yio gba kọja Gẹrẹ bi aba ti fi awọn oke wọnyi s'lẹ ni ọkọ na yio kọja lọ lori omi Odo Ogun Bi enia ko ba nkiyesi ara ti o ba lo yọ ori yio fi ori gba irin kereni odo Ọṣun.

Bi o ba ti ku bi bnsọ kan ki ọkọ de Ibadan ni iwọ yo ti ma wo oke Mapo, B'ọkọ ba de odo Ọba lati Ibadun iwọ yio ri omi odo Ọba ati nigbati ọkọ ba wa lori ere ni Iwo, iwo yio ma ri omi odo Ọṣun li okere ti o ba si de Ede iwọ yio tun ri odo Ọṣun nitori ati nigbati ọkọ ba nlọ si Oshogbo ọkọ yio kọja lori odo Ẹyinlẹ.

Nigbati ọkọ ba ikuro ni Erin ilẹ ti o nlọ si Offa iwọ yio ri ẹnu ala Igbo at'ọdan ni Offa iwọ yio ri omi afẹ lẹlẹ ni Ilọrin iwọ yio ri odo Asa ati oke Ṣobi nisisiyi ọkọ wa gunlẹ si Jẹbba nibiti mo gbe ti ra ọbẹ ẹja tutu, aṣẹ ni gbogbo irin ti a ti nba bọwa, ọkọ wa koiti sare rara, awọn oṣiṣẹ Reluwe npe ọkọ ti o mu wa kuro ni Jẹbba ni Double Tender.

Nṣe ni ọkọ yi nsare lọ bi mọnamọna larin apata lọtun apata ati losi titi a fi de akeri eyiti awọn oṣiṣẹ Reluwe npe ni alafara mẹrindinlogun titi le ọkọ wa gba ori odo alhoyaya ti a npe ni odo Kaduna kọja a si gunlẹ si Teṣan Sunguru nibiti mo gbe ra irori kan

Oke kan wa nigbati a ba fi ilu Mina silẹ nigbati oko ba ngba ẹgbẹ Oke yi koja lo, iwo yio ma ri awon ejo nlanla ti o wa ya oringbẹ oko gunlẹ si Kano. Ni hin yi ni a ba awon ti o nlo si Kauo ati eyiti o nlo PorstHarucort.

A ṣe ni gbogbo ohun ti O ti nri bọ wa loju ọna a koiti ri nkọkan rara, nigbati a de Iri, awọn enia ibẹ ko ni ohun meji ti nwọn fi nṣe owo ti o tayọ ata ilẹ, Ọkọ wa gunlẹ si Kafanchan nwọn ni yio pẹ diẹ ki ọkọ wa to ṣi, nwọn nduro de kọ Jos mo lọ silẹ mo ba awọn ero lọ si ọja ibẹ ni mo ti ri pe enia du du nṣe Aọta.

Nisisiyi ọkọ Jos de, a si mba irin ajo wa lọ. Bi enia ba duro ni Kafanchan yio ma ri awọn oke nlanla li ọna Jos. Nigbati ọkọ wa de ilu kan ti nwọn npe ni lafia, o fẹrẹjẹ wipe adẹtẹ ni gbogbo awọn ara ilu.

Wo Oju Ewe Kẹfa

### Lati Oju 'we Keji

Ma fi wa silẹ lailai
Ayọ ti ko l'opin
On 'bukun yio jẹ tiwa
Pawa mọ n'nu ore
Tọ wa gba la damu
Yo wa ninu ibi
Laiye ati lọrun.
Ka tiyin on ọpẹ
F'Ọlọrun baba ọmọ
Atẹmi Mimọ
Ti o gaju lọ'run
Ọlọrun kan lailai
Laiye ati ọrun mbọ
Bẹ lo wa disiyi
Bẹni yio wa lailai Amin.

Niti oludasilẹ, olutu ati oṣiṣẹ irohin yoruba, adura mi ni pe ki Edumare ran yin lọwọ ninu igbokegbodo yin, ẹ koni ṣiṣe ẹ koni ṣikọe Ko ni ṣi tẹ. ọkọ Ọba ko ni ṣa yin ni ẹsẹ. Ti o ba si wa yin ni ẹsẹ ko ni ran yin lagbara Odua Toripe awọn babanla wa ni i maa sọ bayi pe, "Akii ridi okun, bẹẹni a ki i ridi ọsa, ọmọnigedegede ki i jẹ a ridi on a ki i si ri ibiti oyin fi nṣe afara, Ọmọ araiye ko ni ri gbogbo wa o,

Lakotan ara, mo ki ẹnyin ti ẹ nkọwesi iwe Irohin Imọlẹ pe, ẹ ku ajọyọ ọdun ẹ ju ti iwe na waiye ni ilu Eko Aṣeyi ṣ' p odun o Ajumọṣe temi ati Irohin Imọlẹ ko ni bajẹ o

## Bi O Tilẹ Jẹ Pe Ede Ati Aṣa Yatọ, Sibẹ, Okan Na Ni Wa !



Irohin ko to afojuba ni ariya ayẹyẹ ti awọn enia ṣe fun Ọgbẹni Zdenek Macurasti aya rẹ, ti nwọn iṣẹ akọwe ninu ile iṣẹ Aṣoju Ijọba ilẹ Czechoslovakia ni Naijiria eyiti Ọgbẹni ati Iyawo Ọmọtayọ ṣe fun awọn enia mejeji ninu ile won ni opin ọsẹ to kọja lo yi.

Ọgbẹni Ọmọtayọ jẹ ọkan ninu awọn oniṣowo atata ni igboro iluu Eko, nigbati nwọn gbọ wipe Ọgbẹni Zdenek ati aya rẹ yio kuro ni ilẹ Naijiria lọ si ilu wọn laipẹyi, ni nwọn ba pe awọn enia na sinu ile wọn lati ṣe ẹyẹ idagbere fun wọn.

Ṣugbọn nigbati inawo ọjọ na bẹrẹ Ọgbẹni Ọmọtayọ fun awọn Oyinbo na ni awọn aṣọ ilẹ wa ti ọkọ ati iyawo rẹ ni ọjọ na.

Awọn Ọgbẹni Zdenek ati Iyawo Ọgbẹni Ọmọtayọ ni ẹ nwo ninu aworan yi ti awọn mejeji njo bi koko. Onirohin wa Ejongboro ti o lọ si ibi inawo ọjọ na fi ye wa wipe, inu awọn Oyinbo na dun pupọ nigbati nwọn wọ aṣọ na o ṣi tun jọ wọn loju pupọ

Awọn enia jankanjankan ti nwọn wa sibi inawo ọjọ na ti pọju ohunti a tun le maa daruko wọn lọ.

